8. Emi si gbọ, ṣugbọn kò ye mi: nigba naa ni mo wi pé, "Oluwa mi, kinni yoo ṣe ikẹhin nkan wọnyìí?" (ẹsẹ 6.)
9. O si wi pe, "Maa ba ọ̀nà rẹ lọ, Danieli, nitori ti a ti sé ọ̀rọ̀ naa mọ́ sọhun, a sì fi èdìdí dí i titi fi di ìgbà ikẹhin. (ẹsẹ 13:4.)
10. Ọpọlọpọ ni a o wẹ̀ mọ́, wọn o si di funfun, a o si dán wọn wò: ṣugbọn awọn ẹni-buburu yoo maa ṣe buburu: gbogbo awọn eniyan buburu ki yoo kiyesi i; ṣugbọn awọn ọlọgbọn ni yoo kiyesi i. (Dan 11:35; Isa 32:6,7.)
11. Ati lati ìgbà àkókò ti a o mu ẹbọ ojojumọ kuro, ati lati gbé irira isọdahoro kale, yoo jẹ eedégbèje ó dín mewàá ọjọ. (Dan 8:11-14; 9:27; 11:31; Matt 24:15; Luk 21:24.)
12. Ibukun ni fun ẹni ti o duro de e, ti ó si dé òji lé lẹẹdegbeje ó din márùn ọjọ naa. (Isa 30:18; Ifh 11:2; 12:6; 13:5.)
13. Ṣugbọn iwọ maa bá ọ̀nà rẹ lọ, titi òpin yoo fi dé, iwọ o si sinmi, iwọ o si dide duro ni ipò rẹ ni ìkẹ́hìn ọjọ." (ẹsẹ 9,14; Ifh 14:13.)

28

# HOSEA

**(B.C. 785–725)**

ORI 1.

**Akọlé.**

ỌRỌ̀ Oluwa ti o tọ Hosea, ọmọ Beeri wa, ni ọjọ́ Ussiah, Jotamu, Ahasi, ati Hesekiah, awọn ọba Juda, ati ni ọjọ Jeroboamu ọmọ Joasi, ọba Israẹli. (Rom 9:25; 2 A.Ọba 15:1–7; 2 Kro 27:1–9; 2 A.Ọba 16:1–20; 2 Kro 29:1–32; 2 A.Ọba 13:13; 14: 23–29.)

**Hosea fẹ Gomeri.**

2. Ibẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ Oluwa si Hosea, Oluwa si wi fun Hosea pe, "Lọ, fẹ alágbèrè obinrin kan fun ara rẹ, ki o sì bí awọn ọmọ panṣága; nitori ilè yìí ti ṣe àgbèrè gidigidi kúrò lẹhin Oluwa." (Hos 3:1; Jer 3:1,12,14; Hos 2:5; 3:5.)
3. O si lọ o si fẹ Gomeri ọmọbinrin Diblaimu; ẹni ti o lóyún, ti o si bi ọmọkunrin kan fun un.
4. Oluwa si wi fun un pe, "Pe orukọ rẹ̀ ni Jesreeli; nitori niwọn ìgbà diẹ, emi o bẹ ẹ̀jẹ̀ Jesreeli wò lara ile Jehu, emi o si fi òpin si ijọba ile Israeli. (2 A.Ọba 10:1–14;15:10.)
5. Yoo si ṣe ni ọjọ naa, emi o ṣẹ́ ọrún Israẹli ni àfonífojì Jesreeli." (2 A.Ọba 15:29.)
6. O si tun lóyún, o si bi ọmọbinrin kan. Ọlọrun si wi fun un pe, "Pe orukọ rẹ̀ ni *Loruhama: nitori emi ki yoo tun ṣaanu fun ilé Israẹli mọ́, nitori ti emi o mu wọn kuro. (ẹsẹ 3,9; Hos 2:4.)
7. Ṣugbọn emi o ṣaanu fun ile Juda, emi o si fi Oluwa Ọlọrun wọn gba wọ́n là, emi ki yoo si fi ọrún, tabi idà, tabi ogun, ẹṣin, tabi ẹlẹṣin gbà wọ́n là." (Isa 30:18; Jer 25:5,6; Sek 9:9,10.)
8. Nigba ti o gba ọmú lẹnu Loruhama, o si loyun o si bi ọmọkunrin kan.
9. Nigba naa ni Ọlọrun wi pe, "Pe orukọ rẹ̀ ni *Loammi; nitori ẹ̀yin ki ṣe eniyan mi, emi kii si ṣe Ọlọrun yín. (ẹsẹ 6.)

**Asọtẹlẹ nipa Ìmú pada bọ sípò.**

10. Ṣugbọn iye awọn ọmọ Israẹli yoo ri bi yanrìn òkun, ti a kò lè wọ̀n ti

---

(6) *Loruhama tumọ si 'ẹni ti a kò ṣaanu fún'.
(9) *Loammi tumọ si 'wọn kii ṣe eniyan mi'.

a kò sì lè kà; ni ibi ti a gbe ti wi fun wọn pe, "Ẹyin ki i ṣe eniyan mi, "A o wi fun wọn pe, "Ẹyin ni ọmọ Ọlọrun alaaye." (Gen 32:12; Jer 33:22; Rom 9:25–27; ẹsẹ 9; Isa 63:16; 64:8.)

11. Nigba naa ni a o kó awọn ọmọ Juda ati awọn ọmọ Israẹli jọ pọ̀, wọn yoo si yan olori kan fun ara wọn, wọn yoo sì jade kuro ni ilẹ naa; nitori nla ni ọjọ́ Jesreeli yoo jẹ. (Isa 11:12; Jer 23:5,6; Esk 37:21–24; Hos 3:5.)

ORI 2.

**Gomeri jẹ́ apẹẹrẹ àgbèrè Israẹli.**

Ewi fun awọn arakunrin yin, "Ammi;" (ẹyin ni eniyan mi) ati fun awọn arabinrin yin, "Ruhama" (ẹni ti o ti ri aanú gbà. (ẹsẹ 23.)

2. "Ẹ ba ìyá yin wíjọ́, ẹ wijọ; nitori oun ki i ṣe aya mi, bẹẹ ni emi ki i ṣe ọkọ rẹ̀: nitori naa jẹ ki o mu gbogbo àgbèrè rẹ̀ kúrò ni iwaju rẹ̀, ati gbogbo panṣaga rẹ̀ kúrò laarin ọyàn rẹ̀. (Hos 4:5; ẹsẹ 5; Isa 50:1; Hos 1:2.)

3. Ki emi má bà tu u si ìhòhò, emi o si gbe e kalẹ bi ọjọ ti a bi i, emi o si ṣe e bi ijù, emi o si gbe e kalẹ bi ilẹ gbigbẹ, emi o si fi oungbẹ pa a kú. (Esk 16:7,22,39; Isa 32:13,14; Amos 8:11.)

4. Emi ki yoo si ṣaanu fun awọn ọmọ rẹ̀; nitori ti wọn jẹ́ ọmọ àgbèrè. (Jer 13:14; Esk 8:18.)

5. Nitori ti ìyá wọn ti huwa panṣaga obinrin: ẹni ti o lóyún wọn ti ṣe ohun ìtìjú: nitori ti o wi pe, 'Emi o tún tọ awọn ayanfẹ mi lẹhin, ti nfun mi ni ounjẹ mi ati omi mi, irun agutan mi ati ọ̀gbọ̀ mi, òróró mi, ati ohun mímu mi.' (Isa 1:21; Jer 3:1,2,6; 44:17,18.)

**Idajọ Gomeri.**

6. Nitori naa kiyesi i, emi o fi ẹ̀gún ṣagbara yí ọ̀nà rẹ ká, emi o si mọ odi, ti oun ki yoo fi ri ọ̀nà rẹ̀ mọ. (Job 3:23; 19:8; Hos 9:6; 10:8.)

7. Oun o si lepa awọn ayanfẹ rẹ̀, ṣugbọn ki yoo lè bá wọn; oun o si wá wọn, ṣugbọn ki yoo ri wọn: nigba naa ni yoo wi pe, 'Emi o pada tọ ọkọ mi iṣaaju lọ; nitori ti o san fun mi nigba naa ju ti isinsinyìí lọ.' (Jer 2:2; 3:1; Esk 16:8; Hos 13:6.)

8. Nitori oun kòì tíì mọ̀ pe emi ni ẹni ti o fun un ni ọkà, ati ọti-waini titun, ati òróró; ti mo si mú fadaka ati wura rẹ̀ pọ̀ si i, ti wọn fi ṣe Baali. (Isa 1:3; Esk 16:19; Hos 13:6.)

9. Nitori naa ni emi o ṣe pada, emi o si mu ọkà mi kúrò ni akoko rẹ̀, ati ọti-waini mi ni ìgbà rẹ̀, emi o si gba irun agutan ati ọ̀gbọ̀ mi pada, ti mo ti fi fun un lati bò ihoho rẹ̀. (Hos 8:7; 9:2.)

10. Ni isinsinyìí ni emi o ṣí ìtìjú rẹ̀ sílẹ̀ lójú awọn ayanfẹ rẹ̀, ẹnikẹni ki yoo si gba a lọwọ mi. (Esk 16:37.)

11. Emi o si fi opin si gbogbo ayọ rẹ, ọjọ àsè rẹ, oṣu titun rẹ, ọjọ isinmi rẹ, ati gbogbo ọjọ àsè òwò rẹ. (Jer 7:34; 16:9; Amos 8:10; Isa 1:13,14.)

12. Emi o si pa ajara rẹ̀ ati igi ọpọtọ rẹ̀ run, ni ti awọn ti o ti wi pe, 'Awọn wọnyìí ni èrè mi ti awọn ayanfẹ mi ti fi fun mi,' emi o si sọ wọn di igbó, awọn ẹranko ìgbẹ́ yoo si jẹ wọ́n. (ẹsẹ 5; Isa 5:5; Hos 13:8.)

13. Emi o si bẹ ọjọ́ Baali wò lára rẹ̀, nínú èyí ti o fi tùràrí jóná fun wọn, ti o fi oruka etí, ati ohun ọ̀ṣọ́ rẹ̀, ṣe ara rẹ̀ lọṣọ, ti o si tọ awọn ayanfẹ rẹ̀ lẹhin lọ, ti o si gbàgbé mi, ni Oluwa wi. (Esk 16:12,17; Hos 4:6; 8:14; 13:6.)

**Ileri lati mu Gomeri padabọ sípò.**

14. "Nitori naa kiyesi i, emi o tan an, emi o sì mu un wa si aginju, emi o si sọrọ itunu fun un. (Esk 20:33–38.)

15. Emi o si fun un ni ọgbà ajara rẹ̀ lati ibẹ̀ lọ, ati àfonífojì Akori fun ìlẹ̀kùn ireti: oun o si maa kọrin nibẹ, bi lọjọ èwe rẹ̀, ati bi lọjọ ti o jáde wá lati ilẹ Egipti. (Esk 28:25,26; Jos 7:26; Jer 2:2; Eks 15:1,2; Hos 11:1.)

16. "Yoo si ṣe ni ọjọ́ naa, iwọ o pè mí ní 'Ọkọ mi'; iwọ ki yoo si pe mi ni 'Baali' mọ, ni Oluwa wí,

17. Nitori emi o mu orukọ awọn Baali kuro lẹ́nu rẹ̀, a ki yoo si fi orukọ

wọn ranti wọn mọ. (Eks 23:13; Jos 23:7; Psm 16:4; Sek 13:2; ẹsẹ 13.)

18. Ni ọjọ naa ni emi o si fi awọn ẹranko ìgbẹ́, ati ẹyẹ ojú ọ̀run, ati ohun ti nrakò lori ilẹ̀ dá majẹmu fun wọn, emi o si ṣẹ́ ọrún ati idà ati ogun kuro ninu ayé, emi o si mu wọn dubulẹ ni ailewu. (Job 5:23; Isa 11:6–9; Psm 46:9; Esk 34:25.)

19. Emi o si fẹ ọ fun ara mi titi lae; nitootọ, emi o si fẹ ọ fun ara mi ni ododo, ni idajọ, ati ni ìyọ́nú, ati ni aanu. (Isa 62:4,5; Jer 3:14; Isa 1:27.)

20. Emi o tilẹ fẹ ọ fun ara mi ni otitọ iwọ o si mọ Oluwa. (Hos 6:6; 13:4.)

21. Yoo si ṣe ni ọjọ naa, emi o dahun, emi o da awọn ọ̀run lohun, wọn o si da ayé lohun; ni Oluwa wí. (Isa 55:10; Esk 8:12.)

22. Ilẹ yoo si dá ọka, ati ọti-waini, ati ọ̀róró, lohun; wọn o si dá Jesrẹeli lohun. (Jer 31:12; Joel 2:19.)

23. Emi o si gbin in fun ara mi lori ilẹ̀, emi o si ṣaanu fun ẹni ti kò ti ri aanu gbà; emi o si wi fun awọn ti ki i ṣe eniyan mi pe, 'Iwọ ni eniyan mi,' oun o si wi pe, 'Iwọ ni Ọlọrun mi.'" (Jer 31:27; Hos 1:6; 1:9,10; Sek 13:9; Rom 9:25,26.)

## ORI 3.

**A ti ṣe aṣepe iṣẹ imu pada bọ Gomeri.**

OLUWA si wi fun mi pe, "Tun lọ, fẹ́ obinrin kan ti o jẹ́ olùfẹ́ ọrẹ rẹ, ti o si nṣe panṣaga; gẹgẹ bi Oluwa ti fẹ́ awọn ọmọ Israẹli, ṣugbọn ti wọn yípadà si ọlọrun miran, ti wọn si nfẹ akara èso àjàrà." (Hos 1:2; 2 Sam 6:19; 1 Kro 16:3.)

2. Bẹẹ ni mo ra a fún ara mi ni fadakạ mẹẹdogun, ati homeri barli kan pẹlu ààbọ̀: (Rut 4:10.)

3. Mo si wi fun un pe, "Iwọ yoo ba mi gbe lọjọ pupọ; iwọ ki yoo si huwa àgbèrè, iwọ ki yoo si jẹ ti ọkunrin miran: bẹẹ ni emi o jẹ tirẹ pẹlu."

4. Nitori ọjọ pupọ ni awọn ọmọ Israẹli yoo gbe laini ọba, tabi olórí, ati laini ẹbọ, tabi ère, ati laini ẹfodi tabi terafimu. (Hos 13:10,11; 2:11; Eks 28:6; Ondj 17:5; Sek 10:2.)

5. Lẹhin naa awọn ọmọ Israẹli yoo pada, wọn yoo si wa Oluwa Ọlọrun wọn, ati Dafidi ọba wọn; wọn yoo si bẹru Oluwa, ati ore rẹ̀ lọjọ ikẹhin. (Jer 50:4,5; Esk 34:23,24; Jer 31:9; Mika 4:1.)

## ORI 4.

**Iwa panṣágà awọn Ọmọ Israẹli.**

Ẹgbọ ọ̀rọ̀ Oluwa, ẹyin ọmọ Israẹli; nitori Oluwa ni ẹjọ́ kan pẹlu awọn ara ilẹ naa, nitori ti kò si otitọ, tabi aanu, tabi imọ Ọlọrun ni ilẹ naa. (Hos 5:1; 12:2; Mika 6:2; Isa 59:5; Jer 7:28; Hos 6:6; 5:4.)

2. Ibura wà níbẹ̀, ati èké, ati ìpani, ati olè, ati ìṣe panṣaga; wọn tú jade, ìtàjẹ̀sílẹ̀ sì nkan ìtàjẹ̀sílẹ̀. (Hos 10:4; 7:3; 6:9; 7:1,4; 6:8.)

3. Nitori naa ni ilẹ̀ naa yoo ṣe ṣọ̀fọ̀, ati olukuluku ẹni ti ngbe inú rẹ̀ yoo rẹ̀ dànù, pẹlu awọn ẹranko igbẹ, ati pẹlu awọn ẹyẹ oju ọ̀run; a o si mu awọn ẹja inu òkun kuro pẹlu. (Jer 4:28; Sef 1:3; Jer 4:25.)

4. Ṣugbọn má jẹ ki ẹnikẹni jà, tabi ki o bá ẹnikeji rẹ̀ wi: nitori awọn eniyan rẹ̀ dabi awọn ti nba alufa jà. (Esk 3:26; Deut 17:12.)

5. Ìwọ yoo si ṣubú ni ọ̀sán, woli si ṣubu pẹlu rẹ ni alẹ́, emi o si ge ìyá rẹ kuro. (Hos 5:5; Esk 14:3,7; Hos 2:2,5.)

6. A ge awọn eniyan mi kuro nitori àìní ìmọ̀: nitori ìwọ ti kọ ìmọ̀ sílẹ̀, emi o si kọ̀ ọ́, ti iwọ ki yoo ṣe alufa mi mọ́: niwọn bi iwọ ti gbàgbé ọ̀fin Ọlọrun rẹ, emi pẹlu o gbagbe awọn ọmọ rẹ. (ẹsẹ 1; Mal 2:7,8; Hos 2:13; 8:1,12.)

7. Bi a ti mu wọn pọ si i to, bẹẹ naa ni wọn si dẹ́ṣẹ̀ si mi tó: nitori naa emi o yi ògo wọn pada si ìtìjú. (Hos 10:1; 13:6; Hab 2:16; Mal 2:9.)

8. Wọn njẹ ẹ̀ṣẹ̀ awọn eniyan mi, wọn si gbe ọkan wọn si aṣedeede wọn. (Hos 10:13; Isa 56:11.)

9. Yoo si ṣe, gẹgẹ bi eniyan, bẹẹ ni alufa: emi o si bẹ̀ wọn wo nitori ọ̀nà wọn, emi o si san èrè iṣẹ wọn pada fun wọn. (Isa 24:2; Jer 5:31; Hos 9:9.)

10. Wọn o si jẹ, wọn ki yoo si yó: wọn o ṣe àgbèrè, wọn ki yoo si pọ̀ si i nitori wọn ti fi ṣiṣe-akiyesi Oluwa silẹ. (Lef 26:26; Mika 6:14; Hos 7:14; 9:17.)

11. Agbere ati ọti-waini, ati ọti-waini titun ti gba eniyan lọkan. (Hos 5:4; Isa 28:7.)

12. Awọn eniyan mi nbeere ìmọ̀ lọ́wọ́ igi wọn, ọpa wọn si nfi han fun wọn: nitori ẹ̀mí agbere ti mu wọn ṣìnà, wọn si ti ṣe agbere lọ kuro labẹ Ọlọrun wọn. (Jer 2:27; Hab 2:19; Hos 5:4; 9:1.)

13. Wọn rubọ lori awọn òkè-nla-nla, wọn si sun tùràrí lori awọn òkè kékèké, labẹ igi oaku ati igi poplari ati igi elmu, nitori ti òjìji wọn dara: nitori naa awọn ọmọbinrin yin yoo ṣe àgbère, ati awọn àfẹ́sọna yin yoo ṣe panṣaga. (Jer 3:6; Esk 6:13; Hos 2:13; 11:2; Amos 7:17; Rom 1:28.)

14. Emi ki yoo ba awọn ọmọbinrin yin wi nigba ti wọn ba ṣe àgbèrè, tabi awọn àfẹ́sọna yin nigba ti wọn ba ṣe panṣaga: nitori ti awọn ọkunrin ti yà sapakan pẹlu awọn àgbèrè, wọn si nba awọn panṣaga rubọ: nitori naa awọn eniyan ti ko ba mòye yoo ṣubu. (ẹsẹ 18; Deut 23:17; ẹsẹ 6,11.)

15. Bi o tile jẹ pé iwọ, Israẹli, ṣe panṣaga, máṣe jẹ ki Juda ṣe; ẹ má si ṣe wa si Gilgali, ẹ má sì ṣe gòkè lọ si Bet-afeni, ẹ má si ṣe búra pe, "Oluwa nbẹ."

16. Nitori Israẹli ṣe agídí bi ọmọ maalu alágídí; ṇi isinsinyìí Oluwa yoo bọ́ wọn bi ọ̀dọ́-agutan ni ibi àyè nla. (Psm 78:8; Isa 5:17; 7:25.)

17. Efraimu ti dàpọ̀ mọ́ òrìṣà, fi i silẹ. (Psm 81:12; ẹsẹ 4.)

18. Wọn mu ohun-mímu wọn tán, wọn ṣe panṣaga lọ, ifẹ wọn si ohun-ìtìjú ga pupọ̀ ju ohun ìyìn lọ. (ẹsẹ 14,7.)

19. Afẹfẹ kan yoo ká wọn pọ̀ mọ́ ìyẹ́ apa wọn, wọn o si tijú nitori ẹbọ wọn. (Hos 12:1; 13:15; Isa 1:29.)

ORI 5.

**Ọlọrun yoo rorò mọ awọn ọmọ Israẹli.**

Ẹgbọ́ èyí, èyin alufa: si tẹtisilẹ ẹyin ile Israẹli; ki ẹ si gbọ, ile ọba! nitori idajọ kàn yin, nitori ti ẹyin jẹ idẹkun si Mispa, àwọ̀n ti a nà silẹ lori Tabori. (Hos 4:1; 6:9.)

2. Awọn ọlọ̀tẹ̀ si jinlẹ ni pipanirun, emi o jẹ olubawi gbogbo wọn.

3. Emi mọ Efraimu, Israẹli kò si pamọ fun mi: nitori ni isinsinyìí Efraimu, iwọ ṣe agbere, Israẹli si dibajẹ. (Amos 3:2; Hos 6:10.)

4. Iṣe wọn ki yoo fun wọn laaye lati yipada si Ọlọrun wọn: nitori ẹ̀mí agbere wà laarin wọn, wọn kò si mọ Oluwa. (Hos 4:11,12.)

5. A si rẹ ogo Israẹli silẹ loju ara rẹ̀; nitori naa ni Israẹli ati Efraimu yoo ṣubu ninu aiṣedeede wọn, Juda yoo si ṣubu pẹlu wọn. (Hos 7:10; 4:5; Esk 23:31–35.)

6. Wọn yoo lọ pẹlu awọn agbo-ẹran wọn ati ọ̀wọ́ ẹran wọn lati wa Oluwa ṣugbọn wọn ki yoo ri i, o ti fa ara rẹ̀ sẹhin kuro lọdọ wọn. (Mika 6:6,7; Isa 1:15; Esk 8:6.)

7. Wọn ti hùwà arekereke si Oluwa nitori wọn ti bí ajeji ọmọ: ni isinsinyìí ni ọṣu titun yoo jẹ wọn run, pẹlu ìpín wọn. (Isa 48:8; Hos 6:7; 2:4,11,12.)

8. Ẹ fun fèrè ni Gibea, ati ìpè ni Rama: kigbe kikan ni Bet-afeni, wariri, iwọ Bẹnjamini. (Hos 9:9; 10:9; Isa 10:29,30; Hos 4:15.)

9. Efraimu yoo di ahoro lọjọ ibawi; ninu awọn ẹ̀yà Israẹli ni emi ti fi ohun ti o wà nitootọ hàn. (Isa 37:3; 46:10; Sek 1:6.)

10. Awọn olori Juda dabi awọn ti o yẹ oju ààlà: lara wọn ni emi o tu ibinu mi sí bi omi. (Deut 19:14; Esk 7:8; Psm 93:3,4.)

11. A tẹ orí Efraimu ba, a si ṣẹgun rẹ̀ ninu idajọ, nitori ti o mọ̀ọ́mọ̀ tẹle òfin naa. (Hos 9:16.)

12. Nitori naa ni emi o ṣe dabi kokoro aṣọ si Efraimu, ati si ile Juda bi ìdin. (Psm 39:11; 12:4.)
13. Nigba ti Efraimu ri àrùn rẹ̀, ti Juda si ri ọgbẹ́ rẹ̀, nigba naa ni Efraimu tọ ara Assiria lọ, o si ranṣẹ si ọba Jarebu; ṣugbọn oun kò lè mu ọ lara dá, bẹẹ ni kò lè wo ọgbẹ́ rẹ jinná. (Jer 30:12; Hos 7:11; 8:9; 10:6; 14:3.)
14. Nitori emi o dabi kinniun si Efraimu, ati bi ọmọ kinniun si ile Juda, emi, ani emi o fàya; emi o si lọ, emi o mu lọ, ẹnikẹni ki yoo si gba a silẹ̀. (Hos 13:7,8; Psm 50:22; Mika 5:8.)

**Ironupiwada ati ipadabọ sípò.**

15. Emi yoo pada lọ si ipò mi, títí wọn o fi jẹ́wọ́ ẹ̀ṣẹ̀ wọn, ti wọn yoo si wá ojú mi: nínú ipọnju wọn, wọn yoo wa mi ni kutukutu. (Isa 64:7–9; Jer 2:27; Hos 3:5.)

ORI 6.

Ewá, ẹ jẹ ki a yipada si Oluwa: nitori o ti fà wá ya, ki o lè mu wa lara dá; o ti lù wa, yoo si tun wa dì. (Jer 50:4,5; Hos 5:14; 14:4; Isa 30:26.)
2. Lẹhin ijọ meji, yoo si sọ wá jí: ni ijọ kẹta yoo gbe wa dide, awa yoo si wà laaye ni iwaju rẹ̀. (Psm. 30:5.)
3. Nigba naa ni awa o mọ̀, bi a ba tẹramọ mímọ Oluwa: o ti pèsè ijade lọ rẹ bi owurọ: oun yoo si tọ̀ wá wá bi ọjó: bi àrọ̀-kuro ati akọ́rọ̀ òjò si ilẹ̀." (Isa 2:3; Mika 4:2; Psm 19:6; Mika 5:2; Joel 2:23.)

**Israẹli tun pada si ìwà aiṣootọ́ wọn.**

4. Efraimu, kinni emi o ṣe si ọ? Juda, kinni emi o ṣe si ọ? Nitori ifẹ yin dabi ikuuku owurọ, ati bi ìrì kutukutu ti o kọja lọ. (Hos 7:1; 11:8; 13:3.)
5. Nitori naa ni mo ṣe fi ààké ge wọn lati ọwọ́ awọn woli; mo ti fi ọ̀rọ̀ ẹnu mi pa wọn: ki idajọ rẹ̀ le ri bi imọlẹ ti o jade lọ: (Jer 1:10,18; Heb 4:12; ẹsẹ 3.)
6. Nitori àanú ni mo fẹ́, ki i ṣe ẹbọ; ati ìmọ̀ Ọlọrun ju ọrẹ-ẹbọ sisun lọ. (Matt 9:13; Psm 50:8,9; Hos 2:20.)
7. Ṣugbọn bi Adamu wọn ti dá majẹmu kọja; nibẹ ni wọn ti ṣẹtan si mi. (Hos 8:1; 5:7.)
8. Gileadi ni ilu awọn ti nṣiṣẹ ẹ̀ṣẹ̀, a si ti fi ẹ̀jẹ̀ bà á jẹ́. (Hos 4:2.)
9. Ati gẹ́gẹ́ bi ọwọ́ olè ti nlumọ̀ de eniyan, bẹẹ ni ẹgbẹ́ awọn alufa fohunṣọkan lati paniyan lọna Shekemu, nitori ti wọn tẹ̀ siwaju ninu ìwà ipá. (Hos 7:1; Jer 7:9,10; Esk 22:9; 23:27.)
10. Mo ti ri ohun buburu kan ni ile Israẹli: agbere Efraimu wa nibẹ, Israẹli ti bajẹ. (Jer 5:30,31; Hos 5:3.)
11. Iwọ Juda pẹlu, a ti gbe ìkórè kalẹ fun ọ, nigba ti mo ba yí ìgbèkùn awọn eniyan mi pada. (Joel 3:13; Sef 2:7.)

ORI 7.

NIGBA ti emi ba mu Israẹli lára dá, nigba naa ni ẹ̀ṣẹ̀ Efraimu fi ara han, ati iwa-buburu Samaria; nitori wọn ṣèké; olè si wọle, ọlọ́ṣà si nkoni lode. (ẹsẹ 13; Hos 6:4; 11:8; 4:2; 6:9.)
2. Wọn ko si rò ni ọkàn wọn pe, emi ranti gbogbo ìwà-buburu wọn: ni isinsinyìí iṣẹ ara wọn duro yi wọn ka: wọn wà ni iwaju mi. (Hos 8:13; 9:9; Amos 8:7; Jer 2:19; Hos 4:9.)
3. Wọn fi ìwà-buburu wọn mu ki ọba yọ̀; wọn si fi èké wọn mu awọn ọmọ-alade yọ̀. (ẹsẹ 5; Mika 7:3; Hos 4:2; 11:12; Rom 1:32.)
4. Gbogbo wọn ni panṣaga, bi ààrò tí alakara mú gbóná ti o si dáwọ́ kíkoná rẹ duro, lẹhin igba ti o ti po iyẹfun tan, títí yoo fi wu. (Jer 9:2; 23:10.)
5. Ni ọjọ ọba wa, awọn ọmọ-alade ti fi ìgò ọti-waini mú un ṣàìsàn; o na ọwọ rẹ̀ jade pẹlu awọn ẹlẹ́gàn. (Isa 28:1,7,8.)

6. Ọkàn wọn si njó bi ààrò fun ibi; ìbínú wọn nru túú ni gbogbo òru; ni owurọ o njó bi ọ̀wọ́-iná.

7. Gbogbo wọn gbóná bi aaro, wọn ti jẹ awọn onidajọ wọn run; gbogbo awọn ọba wọn ti ṣubú: ko si ẹnikan ninu wọn ti o ke pè mi. (Psm 21:9; ẹsẹ 16; Isa 64:7.)

8. Efraimu, ti da ara rẹ̀ pọ̀ mọ awọn eniyan naa; Efraimu ni akara ti a ko yipada. (Psm 106:9; ẹsẹ 11; Hos 5:13.)

9. Àwọn alejo ti jẹ agbara rẹ̀ run, oun kò sì mọ̀: nitootọ, ewú wa kakiri lara rẹ̀, sibẹ oun kò mọ̀. (Isa 1:7; Hos 4:6.)

10. Igberaga Israẹli 'si njẹri kòó loju; wọn kò sì yipada si Oluwa Ọlọrun wọn, bẹẹ ni fun gbogbo èyí wọn kò sì wá a. (Hos 5:5; ẹsẹ 7,14; Hos 5:4.)

11. Efraimu pẹlu dabi òpè adaba ti kò lọ́kàn; wón ké si Egipti, wọn lọ si Assiria. (Hos 11:11; 4:6,11,14; ẹsẹ 6; Hos 5:13; 8:9; 12:1.)

12. Nigba ti wọn lọ, emi o na àwọn mi lé wọn; emi o mu wọn wa ilẹ̀ bi ẹyẹ oju-ọ̀run; emi o nà wọn, bi ijọ-eniyan wọn ti gbọ́. (Esk 12:13.)

13. Ègbé ni fun wọn! nitori wọn ti sá kuro lọdọ mi: iparun ni fun wọn! nitori wọn ti ṣẹ̀ si mi: bi o tilẹ ṣepe mo ti rà wọ́n pada, ṣugbọn wọn ti ṣe èké si mi. (Hos 9:12,17; Jer 14:10; Esk 34:6; ẹsẹ 1; Matt 23:37.)

14. Wọn kò sì fi tọkantọkan ké pè mi, nigba ti wọn hu lori akete wọn: wọ́n kó ara wọn jọ fun ọkà ati ọti-waini, wọn si ṣọ̀tẹ̀ si mi. (Jer 3:10; Amos 2:8; Mika 2:11; Hos 13:16.)

15. Bi mo tilẹ nkọ́, ti mo si fun apa wọn lókun, sibẹ wọn nrò ibi si mi. (Hos 11:13; Nah 1:9.)

16. Wọn yipada, ṣugbọn ki ṣe si Ọgá-Ogo: wọn dabi ọrún ẹ̀tàn; awọn ọmọ-alade wọn yoo tipa idà ṣubu, nitori irunu ahọn wọn: eyi ni yoo ṣe ẹ̀sín wọn ni ilẹ Egipti. (Psm 78:57; ẹsẹ 7; Esk 23:32.)

## ORI 8.

**Idalẹbi Ọlọrun lori awọn ọmọ Israẹli.**

FI ìpè si ẹnu rẹ, yoo wá bi ìdì si ile Oluwa, nitori wọn ti ré majẹmu mi kọjá, wọn si ti rú ofin mi. (Hos 5:8; Hab 1:8; Hos 6:7; 4:6.)

2. Wọn yoo kigbe si mi pe, Ọlọrun mi, awa Israẹli mọ̀ ọ́. (Hos 7:14.)

3. Israẹli ti gbe ohun rere sọnù; ọta yoo lepa rẹ̀.

4. Wọn ti fi ọba jẹ, ṣugbọn kii ṣe nipasẹ mi: wọn ti jẹ olori, ṣugbọn emi kò sì mọ̀: fadaka wọn ati wura wọn ni wọn fi ṣe oriṣa fun ara wọn, ki a ba lè gé wọn kúrò. (Hos 13:10,11; 2:8.)

5. Ọmọ-malu rẹ ti ta ọ nù, Samaria; ibinu mi ru si wọn: yoo ti pẹ́ tó ki wọn to de ipò ailẹṣẹ? (ẹsẹ 6; Hos 10:5; 13:2; Jer 13:27.)

6. Nitori lati ọdọ Israẹli wa ni eyi; oniṣọ̀nà ni o ṣe e; nitori naa oun ki i ṣe Ọlọrun: sugbọn ọmọ maalu Samaria yoo fọ́ tuutuu. (Hos 13:2.)

7. Nitori wọn ti gbin ẹfuufuu, wọn o si ka ààjà: igi ọkà ti o duro kò rúdì ki yoo si mu ounjẹ wá: bi o ba ṣe pé o mú wá, alejo ni yoo jẹ ẹ (Hos 10:12,13; Isa 66:15; Nah 1:3.)

8. A gbe Israẹli mì: ni isinsinyìí ni wọn o wà laarin awọn keferi bi ohun-èlò ninu èyí ti inu-didun kò sí. (Jer 51:34; Hos 13:15.)

9. Nitori wọn goke lọ si Assiria, kẹtẹkẹtẹ igbẹ ti nnìkàn-jẹ̀ kiri. Efraimu ti bẹ awọn olufẹ lọ́wẹ̀. (Hos 7:11; Jer 2:24; Esk 16:33.)

10. Nitootọ, bi wọn tilẹ ti bẹ ọ̀wẹ̀ laarin awọn orilẹ-èdè, ni isinsinyìí ni emi yoo kó wọn jọ, wọn yoo si kaanu fun ẹrù ọba awọn ọmọ-alade. (Esk 16:37; 22:20; Jer 42:2.)

11. Nitori Efraimu ti tẹ́ pẹpẹ púpọ̀ lati dẹ́ṣẹ̀, pẹpẹ yoo jẹ́ ohun ti nmu nì dẹ́ṣẹ̀ fun un. (Hos 10:1; 12:11.)

12. Mo ti kọwe ohun pupọ fun un nipa òfin mi, ṣugbọn a kà wọ́n sí bi ohun àjèjì. (ẹsẹ 1; Hos 4:6.)

13. Wọn rubọ ẹran ninu ẹbọ ẹran

mi, wọn si jẹ ẹ; Oluwa kò tẹwọgba wọn; ni isinsinyií ni yoo ranti ìwà-buburu wọn, yoo si bẹ ẹ̀ṣẹ̀ wọn wò: wọn yoo pada lọ si Egipti. (Jer 7:21; Hos 7:2; 1 Kor 4:5; Hos 4:9; 9:7; 9:3,6.)

14. Nitori Israẹli ti gbagbe Ẹlẹda rẹ̀, o sì kọ́ aafin pupọ; Juda si ti sọ ilu-olodi di pupọ: ṣugbọn emi o rán iná kan si orí awọn ìlú rẹ̀, yoo si jẹ awọn ibi-agbara rẹ̀ run. (Hos 2:13; 13:6; Jer 17:27.)

ORI 9.

**Israẹli ki yoo ni ọrọ̀ kankan mọ́.**

MA ṣe yọ̀, Israẹli, fun ayọ̀, bi awọn eniyan miran: nitori iwọ ti ṣe agbere lọ kuro lọdọ Ọlọrun rẹ, iwọ ti fẹ́ alágbàṣe ti panṣaga lori ilẹ ipaka gbogbo. (Isa 22:12,13; Hos 10:5; 4:12; Jer 44:17.)

2. Ilẹ ipaka ati ohun ifunti ki yoo bọ́ wọn, ọti-waini titun yoo si tan ninu rẹ̀. (Hos 2:9.)

3. Wọn ki yoo gbe inú ilẹ Oluwa; ṣugbọn Efraimu yoo pada si Egipti, wọn yoo si jẹ ohun aimọ ni Assiria. (Jer 2:7; Hos 8:13; Esk 4:13; Hos 7:11.)

4. Wọn ki yoo ta Oluwa lọrẹ ọti-waini, bẹẹ ni wọn ki yoo mu un ni inú dùn: ẹbọ wọn yoo ri fun wọn bi ounjẹ awọn ti nṣọ̀fọ̀; gbogbo awọn ti o jẹ nínú rẹ̀ ni yoo di alaimọ: nitori ounjẹ wọn ki yoo wá sí ile Oluwa fun ọkan wọn. (Jer 6:20; Hos 5:6; 8:13; Hag 2:14.)

5. Kinni ẹyin o ṣe ni ọjọ àjọ ọ̀wọ̀, ati ni ọjọ́ àsè Oluwa? (Isa 10:3; Jer 5:31;

6. Nitori, sá wò ó, wọ́n sálọ̀ nitori iparun: Egipti yoo hú wọn síta, Memfisi yoo sin wọn; ibi didara fun fàdákà wọn ni wèrèpè yoo jogún: ẹ̀gún yoo wà ninu àgọ́ wọn. (Hos 10:8.)

7. Ọjọ ìbẹ̀wò dé, ọjọ ẹ̀san dé; Israẹli yoo mọ̀: aṣiwere ni woli naa, ẹni ẹ̀mí naa nsinwin; nitori ọpọlọpọ ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀, ati ìrira nla naa. (Jer 10:15; Mika 7:4; Isa 34:8; Jer 16:18; Esk 14:9,10.)

8. Oluṣọ Efraimu wa pẹlu Ọlọrun mi: ṣugbọn okùn pẹyẹpẹyẹ ni woli naa ni ọ̀nà rẹ̀ gbogbo, ati ìrira si ile Ọlọrun rẹ̀. (Hos 5:1.)

9. Wọ́n ti ba ara wọn jẹ́ pupọpupọ̀, bi lọjọ Gibea: nitori naa oun yoo ranti aiṣedeede wọn, yoo bẹ ẹ̀ṣẹ̀ wọn wò. (Isa 31:6; Ondj 19:12; Hos 5:8; 10:9; 7:2; 8:13.)

**Iye awọn eniyan Israẹli yoo dínkù.**

10. Mo ri Israẹli bi eso ajara ni aginju; mo ri awọn baba yin bi àkọ́pọ́n èso lori igi ọ̀pọ̀tọ́ ni àkọ́so rẹ̀: ṣugbọn wọn tọ Baal-peori lọ, wọ́n sì ya ara wọn sọ́tọ̀ fun itiju naa: wọn sì di ìrira bi iru ohun ti wọn nífẹ̀ sí. (Mika 7:1; Jer 24:2; Num 25:3; Hos 4:14; Jer 11:13.)

11. Bi o ṣe ti Efraimu, ogo wọn yoo fò lọ bi ẹyẹ, laisi ìbí, laini ọmọ, ati laini oyún! (Hos 4:7; 10:5; ẹsẹ 14.)

12. Bi wọn tilẹ tọ́ ọmọ wọn dàgbà, ṣugbọn emi o gbà wọ́n lọwọ wọn, ti ki yoo fi ṣẹ́kù eniyan kan silẹ̀ lootọ, ègbé ni fun wọn, nigba ti mo ba lọ kuro lọdọ wọn! (ẹsẹ 16; Hos 7:13.)

13. Efraimu, bi mo ti ri Tire, ti a gbin si ibi daradara: ṣugbọn Efraimu yoo mu ọmọ rẹ̀ jade wá fun apaniyan. (Esk 27:3,4.)

14. Fun wọn, Oluwa, ni ohun ti iwọ yoo fun wọn? Fun wọn ni inu ti nṣẹyun ati ọmú gbigbẹ. (ẹsẹ 11; Luk 23:29.)

15. Gbogbo iwa-buburu wọn nbẹ ni Gilgali; nitori nibẹ ni mo korira wọn; nitori iwa buburu ìṣe wọn, emi o lé wọn kuro ni ile mi, emi ki yoo fẹran wọn mọ́; gbogbo ọmọ-alade wọn ni ọlọ̀tẹ̀. (Hos 4:9; 7:2; 12:2; Isa 1:23.)

16. A lu Efraimu, gbongbo wọn gbẹ, wọn ki yoo so èso, bi wọn tilẹ bi ọmọ, ṣugbọn emi yoo pa aayo èso inu wọn. (Hos 5:11; 8:7; ẹsẹ 12.)

17. Ọlọrun mi yoo sọ wọn nù, nitori ti wọn kò fetisi tirẹ̀; wọn yoo si di alarinkiri laarin awọn keferi. (Hos 4:10; Deut 28:65.)

ORI 10.

**Gbogbo awọn orisa Israẹli ni a o parun.**

AJARA eléso púpọ̀ ni Israẹli, ti sì
nso èso rẹ̀. Gẹgẹ bi èso rẹ̀ ti npọ̀
tó, bẹẹ ni o ṣe nkọ́ pẹpẹ síi: bí ilẹ̀ rẹ̀ ṣe
ndara sí ni wọn ṣe ngbé ọ̀wọ̀n didara
dide sí. (Esk 15:1–5; Hos 8:11; 3:4.)
2. Ọkan wọn di ẹ̀tàn, ni isinsinyìí ni
wọn o jẹbi; Oluwa yoo wó pẹpẹ wọn
lulẹ, oun yoo si, run ọ̀wọ̀n wọn.
(1 A.Ọba 18:21; Matt 6:24; Hos
13:16; ẹsẹ 8.)
3. Nitori ni isinsinyìí ni wọn o wi pe,
"Awa kò ni ọba, nitori ti awa ko bẹru
Oluwa; njẹ kinni ọba yoo ṣe fun wa?"
(Psm 12:4.)
4. Wọ́n kàn sọ̀rọ̀ sá; pẹlu ìbura èké
wọ́n dá majẹmu: bayìí ni idajọ hù sókè
di igi olóró ninu aporo oko. (Esk
17:13–19; Hos 4:2; Deut 31:16,17.)
5. Nitori awọn ọmọ-malu Bet-afeni,
awọn ti ngbe Samaria yoo bẹ̀rù: nitori
awọn eniyan ibẹ yoo ṣọ̀fọ̀ lori rẹ̀,
ati awọn baba-oloriṣa ibẹ ti o yọ̀ lori
rẹ̀, nitori ogo rẹ̀, nitori o ti lọ kuro
lọdọ rẹ̀. (Hos 8:5,6; 9:11.)
6. A o si mu un lọ si Assiria pẹlu
ẹ̀bùn fun Jarebu ọba: Efraimu yoo gba
itiju, oju yoo si ti Israẹlu nitori ìmọ̀ràn
rẹ̀. (Hos 11:5; 5:13,4,7; Isa 30:3; Jer
7:24.)
7. Bi o ṣe ti Samaria, a o ge ọba rẹ̀
kuro bi ìfofo loju omi. (Hos 13:11.)
8. Ibi giga Afeni, ẹ̀ṣẹ̀ Israẹli, ni a o
parun; ẹ̀gún-ọ̀gan ati ọ̀ṣùṣú yoo hu
jade lori pẹpẹ wọn; wọn o si wi fun
awọn oke nla pe, Bò wa mọlẹ; ati fun
awọn òkè kekeke pe, wó lu wa. (ẹsẹ 5;
1 A.Ọba 12:30; ẹsẹ 2; Hos 9:6; Luk
23:30; Ifh 6:16.)

**Odi Agbara Israẹli ni a o wó lulẹ.**

9. Lati ọjọ́ Gibea ni iwọ ti ṣẹ, iwọ
Israẹli: nibẹ ni wọ́n si dúró si. Ṣé ogun
si awọn ọmọ aláiṣedéédé ni Gibea kò
ha ní lé wọn bá bí? (Hos 5:8; 9:9.)
10. Emi yoo dide si awọn oní-wàkíwà
lati ba wọn wi; a o si gbá awọn
eniyan jọ si wọn, nigba ti mo bá jẹ wọ́n
níyà fún ẹ̀ṣẹ̀ wọn mejeeji. (Esk 5:13;
Hos 4:9.)
11. Efraimu si dabi ọmọ-malu ti a
kọ́, ti o si fẹ lati maa tẹ ọkà; ṣugbọn
emi ti da ọrùn rẹ̀ ti o ni ẹwà si ṣugbọn
emi yoo mu ki a gun Efraimu bi ẹṣin;
Juda yoo tu ilẹ̀, Jakọbu yoo si fọ ọ̀gúlùtu
rẹ̀. (Jer 50:11; Hos 4:16; Jer
28:14; Psm 66:12.)
12. Ẹ furungbin fun ara yin ni ododo,
ẹ ká ni aanu: ẹ tu ilẹ̀ yin ti a kò ro:
nitori ó tó akoko lati wa Oluwa, titi
yoo fi de, ti yoo si fi rọ̀jọ̀ ododo, si yin.
(Owe 11:18; Jer 4:3; Hos 12:6; 6:3;
45:8.)
13. Ẹyin ti tulẹ̀ iwa-buburu, ẹyin ti
ká àiṣedeede; ẹyin ti jẹ eso èké: nitori
iwọ gbẹkẹle ọna rẹ, ati ọpọlọpọ awọn
alagbara rẹ. (Job 4:8; Gal 6:7,8; Hos
4:2; 7:3.)
14. Nitori naa ariwo yoo dide ninu
awọn eniyan rẹ, gbogbo awọn odi
agbara rẹ ni a o si bàjẹ́, bi Salmani ti
ba Betabeli jẹ ni ọjọ ogun: a fọ́ iya
túutúu lori awọn ọmọ rẹ̀. (Isa 17:3;
Hos 13:16.)
15. Bẹẹ ni Beteli yoo ṣe si yin, nitori
iwa-buburu nla yin; ni kutukutu ni a o
ge ọba Israẹli kuro patapata. (ẹsẹ 7.)

ORI 11.

**Assiria yoo ko Israẹli ni ìgbèkùn.**

NIGBA ti Israẹli wa ni ọmọde,
nigba naa ni mo fẹ́ ẹ, mo si pe ọmọ
mi jade wá lati Egipti. (Hos 2:15;
12:9,13; 13:4; Matt 2:15.)
2. Bi mo ba ti npe wọn si, bẹẹ ni
wọn lọ kuro lọdọ mi: wọn rubọ si
Baali wọn si fí tùràrí si ère fínfín.
(2 A.Ọba 17:13–15; Hos 2:13; Isa
65:7; Jer 18:15.)
3. Mo kọ́ Efraimu pẹlu lati rìn, mo
dì wọ́n mú ni apá, sugbọn kò mọ̀ pe
mo ti mu wọn lara dá. (Hos 7:15;
Deut 1:31; Jer 30:17.)
4. Mo fi okùn eniyan fà wọ́n, ati ide
ìfẹ́: mo si ri si wọn bi awọn ti o mu

ajaga kuro ni ẹ̀rẹ̀kẹ́ wọn, mo si gbe ounjẹ kalẹ ni iwaju wọn. (Jer 31:2,3; Lef 26:13; Eks 16:32; Psm 78:25.)

5. Oun ki yoo padà si ilẹ Egipti, ṣugbọn ara Assiria ni yoo jẹ ọba rẹ̀, nitori wọ́n kọ̀ lati yipada. (Hos 10:6; 7:16.)

6. Idà yoo si maa gbe inu ilu rẹ̀, yoo si run ìdábu ilẹ̀kùn rẹ̀, yoo si jẹ wọ́n run, nitori imọran ara wọn. (Hos 13:16; 4:16,17.)

7. Awọn eniyan mi sì tẹ̀ sí pípẹ̀hìndà kuro lọdọ mi: bi o tilẹ ṣe pe wọn pè wọ́n sọ́dọ̀ Ọga-Ogo julọ, wọn kò jùmọ̀ gbe e ga. (Jer 8:5; ẹsẹ 2.)

**Iṣeun-ifẹ Ọlọrun si Israẹli.**

8. Emi o ha ṣe fi ọ silẹ̀, Efraimu! Bawo ni emi o ṣe gba ọ sọnù Israẹli! emi o ha ti ṣe ṣe ọ bi Adma. Bawo ni emi o ṣe ṣe ọ bi Seboimu! Ọkàn mi nyí nínú mi, ìyọ́nú mi, si ngbona sii pẹlu. (Hos 6:4; Gen 14:8; Isa 63:15.)

9. Emi ki yoo mu gbigbona ibinu mi ṣẹ, emi ki yoo yipada lati run Efraimu: nitori Ọlọrun ni emi, ki i ṣe eniyan; Ẹni-Mimọ laarin rẹ: emi ki yoo si wá ninu ibinu. (Deut 13:17; Jer 26:3; Isa 41:14,16; 55:8,9; Mal 3:6.)

**A o mu Israẹli pada bọ sípò.**

10. Wọn o maa tẹle Oluwa: oun o ke ramúramù bi kinniun: nigba ti oun yoo ke, nigba naa ni awọn ọmọ yoo wárìrì lati iwọ-oorun wá. (Hos 6:1–3; Joel 3:16; Isa 66:2,5.)

11. Wọn o wárìrì bi ẹyẹ lati Egipti wá, ati bi àdàbà lati ilẹ Assiria wá: emi o si fi wọn si ile wọn, ni Oluwa wi. (Isa 11:11; 60:8; Esk 28:25,26.)

**Ẹṣẹ Efraimu.**

12. Efraimu fi èké rọgbà yi mi ká, ilé Israẹli, pẹlu ẹ̀tàn: ṣugbọn Juda si dúróṣinṣin sibẹ pẹlu Ọlọrun, ani o ṣe oloótọ́ pẹlu Ẹni-Mímọ́ naa. (Hos 4:2; 7:3.)

ORI 12.

EFRAIMU njẹ afẹ́fẹ́, o si ntọ afẹ́fẹ́ ìlà-oorùn lẹhin ni gbogbo ọjọ́; o nmú èké ati iparun pọ̀ sii lójoojúmọ́, wọn bá awọn ara Assiria dá majẹmu, wọn sì ru òróró lọ sí Egipti. (2. A.Ọba 17:4; Isa 30:6.)

**Idajọ Jakọbu.**

2. Oluwa ni ẹjọ́ kan lati ba Juda rò pẹlu, yoo si jẹ Jakọbu ni ìyà gẹgẹ bi ọ̀nà rẹ̀; gẹgẹ bi iṣe rẹ̀ ni yoo san padà fún un. (Mika 6:2; Hos 4:9.)

3. O di arakunrin rẹ̀ mu ni gìgísẹ̀ ni inu, ati pẹlu agbarà rẹ̀ o ba Ọlọrun jìjàkadì. (Gen 25:26; 32:24,28.)

4. Nitootọ́, o ni agbara lori angẹli, o si bori: o sọkun, o si bẹbẹ lọdọ rẹ̀: o ri i ni Bẹtẹli, nibẹ ni o gbe ba wa sọ̀rọ̀: Gen 32:26; 28:12–15.)

5. Ani Oluwa Ọlọrun awọn ọmọogun; Oluwa ni iranti rẹ. (Eks 3:15.)

6. "Nitori naa, iwọ yipada si Ọlọrun rẹ: pa aanu ati idajọ mọ́, ki o si maa duro de Ọlọrun rẹ ni igba gbogbo." (Mika 6:8; Hos 6:6; Mika 7:7.)

**Alaye kikun lori ẹ̀ṣẹ̀ Efraimu.**

7. Onìṣòwò ti ìwọ̀n ẹ̀tàn nbẹ lọwọ rẹ̀: o fẹ lati nini lara. (Amos 8:5; Mika 6:11.)

8. Efraimu si wi pe, "Ṣugbọn emi di ọlọ́rọ̀, mo ti rí ìní fun ara mi:" Ṣugbọn gbogbo ọrọ rẹ̀ ki yoo lè mú aiṣedéédé rẹ̀ ti ó ti jẹ̀bi kuro. (Hos 13:6; Ifh 3:17; Hos 4:8; 14:1.)

9. Emi ni, Oluwa Ọlọrun rẹ lati ilẹ Egipti wa, yoo si tun mu ọ gbe inu àgọ́, bi ni awọn ọjọ́ àjọ ọ̀wọ̀. (Hos 11:1; 13:4; Lef 23:42; Neh 8:17.)

10. Emi ti sọrọ nipa awọn woli pẹlu, mo si ti mu iran di pupọ, mo ti ṣe ọpọlọpọ àkàwé, nipa ọwọ awọn woli. (2 A.Ọba 17:13; Jer 7:25; Esk 17:2; 20:49.)

11. Aiṣedeede nbẹ ni Gileadi bi? Nitootọ asán ni wọn: wọn rubọ akọ malu ni Gilgali: nitootọ, pẹpẹ wọn dabi ebè ni aporo oko. (Hos 6:8; 4:15; 9:15; 10:1,2.)

12. (Jakọbu si salọ si ilẹ Siria,Israẹli si sìn nitori aya kan; ati nitori aya kan ni ó ṣọ́ agutan.) (Gen 28:5; 29:20.)

13. Ati nipa woli kan ni Oluwa mu Israẹli jade ni Egipti: nipa woli kan ni a si pa oun mọ́. (Eks 13:3.)

14. Efraimu mu un binu kikoro: nitori naa ni yoo fi ẹ̀jẹ̀ rẹ̀ si ori rẹ̀, ẹ̀gàn rẹ̀ ni Oluwa rẹ̀ yoo si san pada fun un. (Esk 18:10–13; Dan 11:18; Mika 6:16.)

ORI 13.

**Iparun Efraimu ni a sọtẹlẹ.**

NIGBA ti Efraimu sọ̀rọ̀, ìwárìrì ni; a gbe e ga ni Israẹli; ṣugbọn o dẹ́ṣẹ̀ ninu Baali, o si kú. (Ondj 8:1; 12:1; Hos 2:8–17.)

2. Ni isinsinyìí, wọn si ndá ẹ̀ṣẹ̀ kún ẹ̀ṣẹ̀, wọn si ti fi fàdákà wọn ṣe ère dídà fun ara wọn, ati oriṣa imọ̀ wọn: iṣẹ oniṣọna ni gbogbo rẹ̀; wọn wi niti wọn pe, Jẹ ki awọn eniyan ti nrubọ fi ẹnu ko awọn ọmọ maalu lẹnu. (Isa 46:6; Hos 8:6.)

3. Nitori naa ni wọn o ṣe dabi ikuukuu owurọ, ati bi ìrì owurọ ti nkọja lọ, bi ìyàngbò ti a ti ọwọ ìjì gbá kuro ninu ilẹ ipakà, ati bi eefín ti njade kuro ninu ile eefín. (Hos 6:4; Dan 2:35; Psm 68:2.)

4. Ṣugbọn emi ni Oluwa Ọlọrun rẹ lati ilẹ Egipti wá, iwọ ki yoo si mọ ọlọrun kan bikoṣe emi: nitori kò si olugbala kan lẹhin mi. (Hos 12:9; Isa 43:11.)

5. Emi ti mọ̀ ọ́ ni aginju, ni ilẹ ti o poungbẹ. (Deut 2:7; 8:15; 32:10.)

6. Gẹgẹ bi a ti bọ́ wọn, bẹẹ ni wọn yó; wọn yo, wọn si gbe ọkan wọn ga; nitori naa ni wọn ṣe gbagbe mi. (Deut 8:12,14; 32:15; Hos 2:13; 4:6; 8:14.)

7. Nitori naa ni emi o ṣe dabi kinniun si wọn; emi o si maa ṣọ wọn bi ẹkùn lẹ́bàá ọna. (E.Jer. 3:10; Jer 5:6.)

8. Emi o pade wọn bi beari ti a gbà ni ọmọ, emi o si fa àwọ̀n ọkàn wọn ya, nibẹ ni emi o si jẹ wọ́n run bi kinniun, ẹranko igbẹ ni yoo fà wọ́n ya. (2 Sam 17:8; Psm 50:22.)

9. Israẹli, iwọ ti pa ara rẹ run, ni ti pe iwọ wà lodi si emi, iranlọwọ rẹ.

10. Nibo ni ọba rẹ gbé wa ni isinsinyìí ninu gbogbo ilu rẹ, ti yoo gba ọ? ati awọn onidajọ rẹ, ni ti awọn ti iwọ wi pe; "Fun mi ni ọba ati awọn ọmọ-alade." (2 A.Ọba 17:4; Hos 8:4.)

11. Emi fun ọ ni ọba ni ibinu mi, mo si mu un kuro ni irunu mi. (1 Sam 8:7; 1 A.Ọba 14:7–10.)

12. A di aiṣedeede Efraimu pọ̀; ẹ̀ṣẹ̀ rẹ̀ la fi pamọ́. (Deut 32:34; Rom 2:5.)

13. Irora obinrin ti nrọbi yoo dé si i: alaigbọn ọmọ ni oun; nitori oun kò duro ni àkókò si ibi ijade ọmọ. (Mika 4:9,10; Isa 37:3; 66:9.)

14. Emi o hà rà wọ́n padà lọ́wọ́ agbara isà-òkú? Emi o hà rà wọ́n padà lọ́wọ́ ikú? Iku, ajakalẹ àrùn rẹ dà? Isa-oku, iparun rẹ dà? Ironupiwàdà yoo pamọ́ kuro loju mi. (Esk 37:12,13; 1 Kor 15:54,55; Rom 11:29.)

15. Bi oun tíle ṣe eléso ninu awọn arakunrin rẹ̀, afẹ́fẹ́ ila-oòrùn kan yoo de, afẹ́fẹ́ Oluwa yoo ti aginju wá, orisun rẹ̀ yoo si gbẹ, ati oju isun rẹ̀ ni a o mu gbẹ; oun yoo ba ohun èlò daradara gbogbo jẹ. (Hos 10:1; Esk 17:10; 19:12; Jer 51:36; 20:5.)

16. Samaria yoo di ahoro: nitori ti o ti ṣọ̀tẹ̀ si Ọlọrun rẹ̀: wọn yoo ti ipa idà ṣubu: a o fọ́ ọmọ wọn tuutuu, ati aboyun wọn ni a o là ni inu. (Hos 10:2; 7:14; Isa 13:16; Hos 10:14; 2 A.Ọba 15:16.)

ORI 14.

**Ìpè si Ironupiwada.**

ISRAẸLI, yipada si Oluwa Ọlọrun rẹ, nitori iwọ ti ṣubu ninu aiṣedeede rẹ. (Hos 10:12; 14:6; Joel 2:13.)

2. Mu ọ̀rọ̀ pẹlu yin, ẹ si yipada si Oluwa: ẹ wi fun un pe, "Mu aiṣedeede gbogbo kuro, si fi oore-ọfẹ gbà wá: bẹẹ ni awa o fi (ọmọ maalu) ètè wa san an fun ọ. (Mika 7:18,19; Heb 13:15.)

3. Assuru ki yoo gba wa; awa ki yoo gun ẹṣin: bẹẹ ni awa ki yoo tun wí mọ́

fun iṣẹ ọwọ́ wa pé, 'Ẹyin ni ọlọrun wa.'
Nitori lọdọ rẹ ni alainibaba gbe ri
aanu.'" (Hos 5:13; Isa 31:1; Hos 8:6;
13:2; Psm 10:14.)

**Ileri ibukun.**

4. Emi o wo ifasẹhin wọn sàn, emi o
fẹ wọn lọ́fẹ̀ẹ́: nitori ibinu mi yi kuro
lọdọ rẹ̀. (Sef 3:17; Isa 12:1.)
5. Emi o dabi ìrì si Israẹli: oun yoo
tanna bi eweko lili; yoo si ta gbòngbò
rẹ̀ bi Lebanoni. (Job 29:19; Matt
6:28; Isa 35:2.)
6. Ẹka rẹ̀ yoo tàn, ẹwà rẹ yoo si dabi
igi olifi, ati òórùn rẹ̀ bi Lebanoni.
(Psm 52:8; O.Sol. 4:11.)
7. Awọn ti o ngbe abẹ ojiji rẹ̀ yoo
pada wa; wọn o sọji bi ọkà: wọn o si
tanna bi ajara: òórùn rẹ̀ yoo dabi ọti-
waini ti Lẹbanoni. (Psm 91:4; Esk
17:23; Hos 2:21,22.)
8. Efraimu yoo wi pe, Kinni emi ni fi
oriṣa ṣe? Emi ti gbọ, mo si ti kiyesi i:
emi dabi igi fírì tútù. Lati ọdọ mi ni a ti
ri eso rẹ̀. (ẹsẹ 3; Isa 41:19; Esk
17:23.)

**Ọ̀rọ̀ ifikun.**

9. Tani o gbọ́n, ti o lè moye nkan
wọnyìí? Tani o ni òye, ti o lè mọ̀ wọn?
Nitori ọna Oluwa tọ́, awọn olododo
yoo si maa rìn ninu wọn ṣugbọn awọn
alárékọjá ni yoo ṣubu sinu wọn. (Psm
107:43; A.A. 13:10; Isa 26:7; 1:28.)

29

# JOELI

**(B.C. 800)**

ORI 1.

**Akolé.**

ỌRỌ̀ Oluwa ti ó tọ Joẹli ọmọ Petu-
eli wá. (Jer 1:2; Esk 1:3; Hos 1:1;
A.A. 2:16.)
2. Gbọ eyi, ẹyin arúgbó, si fi etí silẹ,
gbogbo ẹyin ara ilẹ naa. Eyi ha wà ni
ọjọ yin, tabi ni ọjọ awọn baba yin?
(Hos 4:1; 5:1; ẹsẹ 14; Joel 2:2.)
3. E sọ ọ fun awọn ọmọ yin, ati
awọn ọmọ yin fun awọn ọmọ wọn, ati
awọn ọmọ wọn fun iran miran. (Psm
78:4.)

**Apẹẹrẹ Àjàkálẹ̀ àrun ati Ògbẹlẹ̀.**

4. Eyi ti eeṣú-agenijẹ jẹ kù ni ọ̀wọ́-
eeṣú jẹ; ati eyi ti ọ̀wọ́-eeṣú jẹ kù ni
eeṣú-tata jẹ; eyi ti eeṣú-tata naa sì jẹ
kù ni eeṣú-apanirun miran jẹ. (Deut
28:38; Joel 2:25; Nah 3:15,16; Isa
33:4.)
5. Ji, ẹyin ọ̀mùtí, ẹ si sọkun; pohun-
rere-ẹkun gbogbo ẹyin ọmuti waini,
nitori ọti-waini titun; nitori ti a ge e
kuro ni ẹnu yin. (Joel 3:3; Isa 32:10.)
6. Nitori orilẹ-èdè kan goke wa si ilẹ
mi, o ni agbara, kò si ni iye, ehín ẹni ti
iṣe ehín kinniun o si ni èrìgì abo kin-
niun. (Joel 2:2,11; Ifh 9:8.)
7. O ti pa àjàrà mi run, o si ti ya ẹka
igi ọ̀pọ̀tọ́ mi kurò, o ti bó eepo rẹ̀, o si
sọ ọ nù; awọn ẹka rẹ̀ ni a si sọ di fun-
fun. (Isa 5:6; Amos 4:9.)
8. Ẹ pohunréré-ẹkun bi wundia ti a
fi aṣọ ọ̀fọ̀ di ni àmùrè, nitori ọkọ igba
ewe rẹ̀. (ẹsẹ 13; Amos 8:10.)
9. A ge ọrẹ-jijẹ ati ọrẹ-mimu kuro
ni ile Oluwa; awọn alufa, awọn iranṣẹ
Oluwa, ṣọ̀fọ̀. (Joel 2:14,17.)
10. Oko di igboro, ilẹ nsọ̀fọ̀, nitori a
fi ọkà ṣòfò: ọti-waini titun gbẹ, òróró
nbùṣe. (Isa 24:4,7; Hos 9:2.)
11. Ki oju o ti yin ẹyin àgbẹ̀; ẹ po-
hunrere-ẹkún, ẹyin olutọju àjàrà, ni-
tori alikama ati nitori ọkà barli; nitori
ikore oko ṣègbé. (Jer 14:3,4; Isa 17:
11; Jer 9:12.)